# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 748, MONDAY, JULY 20, 1964 (2D)


## Awọn Ọlọṣa Kọwe Si Onile!

UYO:- Idamu nla ba gbogbo enia nigbati nwọn ji ni kutukutu owurọ ijọta ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi, ti nwọn si ba iwe ti awọn igara Ọlọṣa (ti si fun Onile ki o to wa) to si ẹnu ọna ile wọn pe, ki awọn enia na ma mura silẹ e awọn, awọn nbọ wa ko ẹru wọn.

Ninu iwe na awọn Ọlọṣa na si lọ si isalẹ rẹ pe " Awọn ọmọbinrin ati awọn iyawo nyin ẹleyinju ẹge wọnyi ni afẹ lo ki iṣe awọn ẹru nyin, bi ẹba kọ lati jọwọ wọn silẹ fun wa ti a ba de, a jẹ wipe, ẹmi nyin yio lọ si.

Ijọba lo kọ ile na silẹ ẹgba iwe ti awọn Oluko Ọkunrin ati Obinrin ti nwọn wa ninu ile iwe ni agbegbe na lati ma a gbe ni tosi ile- iwe, nitoripe ile na jina si arin ilu.

Irohin fi ye wa pe, nigbati awọn enia na ji ni owuro, ni gbogbo wọn ba mu iwe na lọ si Teṣan awọn Ọlọpa, lati lọ fi iwe na han wọn peki nwọn wo ohunti awọn ri Ṣugbọn nigbati awọn enia na pada de adugbo na ti ọkan wọn ko balẹ ni gbogbo wọn ba sa jade ninu ile ti nwọn si ko ẹru wọn lọ.

# ROGBODIYAN NLA KAN TUN ṢẸLẸ NI IBADAN!

### Mọto Ayọkẹlẹ Mẹta ati Ile Mẹta Jona Tan Rau-Rau !!

IBADAN:— Gbogbo enia bẹrẹsi sare ọlọmọgbọmọpọn gbogbo ilu si gbọjikan fun ariwo nigbati awọn elegun kan jade ti nwọ si ṣi'le de adugbo kan Idi-Ọlo, Ekotẹdo Ibadan, pẹlu orin ọtẹ ati owe di awọn pẹlu ọbẹ, ada akifọ-igo lọwọ wọn ti awọn kan si s na bọ inu ilu kan ni adugbo na ni ọsan gangan ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi.

Eniti ọran na soju rẹ ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe asiko ọdun egungun ti bẹ rẹ ni Ibadan gbogbo awọn egungun lo si njade ni gbo gbo ilu Ibadan ati agbegbe re lati bi ọjọ mẹta.

Sugbọn nigbati awọn enia kan gbaradi ti nwọn si gbe egungun jade ni ọjọ na nwọn ba ko awọn ohun ija lọwọ ti nwọn doriko ile ọkunrin kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni ni A. J Gbadebo.

Bi o ti ku diẹ ki nwọn de inu ile na ni nwọn ba nkorin Ọt bi nwọn ti de inu ile ọkunrin na ni o ba sare wọ le ti o si gbe ibọn oloju-meji rẹ ti o si yin in si awọn enia na.

Ibọn na ṣe awọn ẹmọ ẹhin egungun na mejila lẹse, ṣugbọn awọn mẹta ni o le pupọ. Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia na sare si ọkunrin na lati gba ibọn ọwọ rẹ ṣugbọn "abẹ la fẹ ese, oko lafẹ ilasa," ọkunrin na fo oju ferese wọle, ni awọn enia na ba sare tọ ọ kawikafọ ni awọn kan ba sana si ile ọkunrin na pe, "oro ti o da mi ni mo da ọ"

Lẹsẹkẹsẹ ni adugbo ba daru ti awọn ara adugbo si nkigbe "ogun de o!" ko pọ pupọ ti awọn ọlọpa ati awọn panadana Ibadan sare de, ṣugbọn nigbati nwọn yio fi pa ina na ten, odidi ile mẹta ati moto ayọkẹlẹ meta Nos WAE 512. LB 2033 ati OOA 1770 loti jona rau rau

Ọkan ninu ọga awọn ọlọpa ọgbẹni Lasisi Ọlatunbosun sọ fun oniwe irohin wa pe, awọn ti gba awọn enia ti nwọn farapa ninu ijamba nu lọ si ile iwosan Ade-ọyọ, awọn si ti mu

WO OJU EWE KẸFA

## Ọba Alaiyeluwa Muṣẹndiku Adeniji Adele Keji Filẹṣaṣọbora!

Eko:- Ẹnu kọ Irohin nibi isin isinku Ologbe alayeluwa, Musẹndiku Adeniji Adele keji Ọba ilu Eko, eyiti gbogbo awọn enia ṣe ninu Iga Iduganran ni deede agogo mẹrin irọlẹ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi.

Ṣiwaju Isinku Ọba Ologbe na ni awọn enia kan ti bẹrẹsi da gbogbo awọn ero ọja ru nipa jijẹ ọja wọn ti nwọn nta ni ọja.

Ọkan ninu awọn enia na fi ye oniwe Irohin wa Ejoagboro pe, Bi Ọba kan ba ku ni Igboro ilu Eko, ko si ẹniti o gbọdọ patẹ tabi si ile itaja rẹ ni ọjọ na. Bi ẹn kan ba si ile itaja rẹ gbogbo ọja ti o ba wa ninu Ile itaja di jijẹ, bi o ba si wipe atẹ onjẹ ni ẹnikan ba lọ pa ni ọja gbogbo ẹ a na ni awọn enia yio jẹ tan patapata.

Nitorina ni awọn enia na ṣe lọ jẹ ọja awọn enia

WO OJU EWE KẸFA



OLOGBE ỌBA ADENIJI ADELE KEJI

# Ekun Rẹrẹ Idajọ Oloye Awolọwọ (Apa 6)



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

## AWỌN ELẸRI ODARAN

Eyi ni orukọ awọn to jẹri gbe awọn ọdaran ti Ijọba be nṣe ejọ ẹsun iditẹ si Ijọba ati igbogun ti Ọba birin Gẹẹsi ati Gomina apapọ Ijọba ilẹ Naijiria awọn enia to jẹri na ni.

Fun Michael Omisade—Iya afin Yetunde Omiside, fun Ayọkọgun Akinsanya ni—Iya afin Christie Akinsanya Iya afin Ajele Akinsanya Iya afin Felicia Shonowo Oloye Moses A. K. Shonowo Dokita Jeremiah,O. Otegbeye ati Francis A Adetola

Ko si eleri fun Samuel Orẹdein ati fun Lateef Jakande awọn eleri to jẹri fun ni Ọgbẹni Clauduis O Olutayọ Ọgbẹni Cyril omekan Nwoke Ọgbẹni Urum O Jemidde Ashafa A. Adigun Ọgbẹni Nicholas B, James Ọgbẹni Horatis N O Agedat Ọebeni Adedoyin Ogunde Ọgbẹni Moses O Olumuyiwa. Ọgbẹni Gani-O Dawodu ati Joseph Loni

Fun Victor Olabisi Onabanjọ ni Ọgbẹni James A Odunlami Ọgbẹni Ọlawọle Folarin Ọgbẹni Russel D carver ati Ọgbẹni John Ikusebiala.

Awọn ẹlẹri fun Gabriel Eyekwonire Ekweyunrt Etchie ni Ọgbẹni John Ikusebiala.

Awọn ẹlẹri fun Semeon Oyeshile ni Ọgbẹni Karimu Salami ati Ọgbẹni Taiwo Salami

Eleri fun J S Tarka ni Ọgbẹni Alfed Amad ati Robinson Iyorsse Ṣugbọn ko si eleri fun J O Lawanson.

Awọn eleri fun oloye Awolowọ ni Ọgbẹni, Benedict Nkpodia Ọgbẹni Bio—dun Falede. Ọgbẹni Jonah Assadugu Ọgbẹni Iyọ Fanami Dokita Victor A Oyesuga Oloye Olu Akin Olugbade. Oba Samuel Akinsaya (Odemọ Oba Ishara) Dokita Samuel A Aluko Dokita Ezekiel A Oluwasani Ọgbẹni Oluwọle Awolọwọ Ọgbẹni Mathew Michael Ọgbẹni Nosike Ikpo, Ọgbẹni Patrcle Atvie. Ọgbẹni John W. Phillps Oloye Samuel O Lanlehin Ọgbẹni Timuthy ibikunle Ojo.



Ọgbẹni J. Ọlawọyin



Ọgbẹni Omishade

## AKOPỌ IDAJỌ NA

Ẹsun ejọ iditẹ si Ijọba ilẹ Naijiria si jẹ ejọ kan ti o jẹ eyi to ga julọ ni ile ẹjọ ilẹ Naijiria ati pe itan ni ẹjọ na yio jẹ nighogho ile ejọ giga ilẹ Naijiria. Ẹjọ na si bẹrẹ ninu ọjọ karun oṣu kọkanla ọdun 1962.

Ni ọjọ ti ile ẹjọ gbe ẹjọ na tide awọn enia mẹtadinlọgbọn ninu awọn enia mọkanlelọgbọn ti ile ẹjọ na fi ẹsun na kan lo fi ara han ni ile ẹjọ ni ọjọ na.

Awọn enia mẹrin ninu awọn ọdaran eyiti awọn ọlọpa nwa ti nwọn ko ri awọn enia na ni Anthony Eronsele Enahoro, Samuel Grace Ikoku, Ayọ Adebanjọ ati James Olubunmi Aluko awọn enia na ni ko fi ara han ni ile ẹjọ na

Nigbati ile ẹjọ na ko bẹrẹ ni adajọ ile ẹjọ na ọgbẹni Sowẹmimọ da awọn enimẹrin silẹ eyiti awọn enia meji si di ajẹri Ijọba awọn enia meji na ni Ọladipọ Maja ati Richard Babalọla

Ni ọjọ karun oṣu kọkanla ọdun 1962 nigbati ile ẹjọ na si kọkọ dẹru kan ẹsun na ati ni ọjọ kejila oṣu kọkanla ọdun 1962 ni ọjọ ti ti ẹjọ na bẹrẹ gan an ọpọlọpọ nkan lo si ṣẹlẹ nigbana.

Ni akọkọ ti ile ẹjọ na bẹrẹ awọn agbẹjọro fun awọn ọdaran na Oloye H. O Davies ati Michael Odẹsanya si ṣe ilana awọn ofin silẹ eyiti awọn agbẹjọro na si nbẹbẹ pe ki ile ẹjọ gba iduro awọn ọdaran na ṣugbọn ile ẹjọ si kọ iduro awọn ọdaran na silẹ

Ni ọna keji awọn agbẹjọro na si tun ṣe ilana ofin miran eyiti awọn agbẹjọro na sọ pe ẹsun ti agbẹjọro fun Ijọba fi mu awọn enia na wa ṣi ile ẹjọ eyiti o jẹ ọjọ kini oṣu kọkanla ọdun 1962 eyi ti awọn agbẹjọro fun awọ ọdaran na sọ pe ko tọna, ṣugbọn adajọ ile ẹjọ na ko gba rara.

Ni ẹkẹta ọgbẹni Adewale Thompson fi ye ile ẹjọ pe agbẹnusọ fun Ijọba to nran ọgbẹni B. A. Adedipẹ lọwọ ọgbẹni S. A Adebiyi ti o jẹ igbakeji Amofin ti Ijọba pe ko ni ẹtọ lati pẹlu ọgbẹni B. A Adedipẹ ati pe ko pẹlu awọn oṣiṣẹ ti ile iṣẹ Agbẹro fun Ijọba ṣugbọn adajọ adajọ ko gba ọrọ ọgbẹni Adewale Thompson.

Ọjọ kejila osu kọkanla ọdun 1962 jẹ ọjọ kan to ga ninu ase ko idajọ na eyiti awọn Ọlọpa mu awọn enia merinlel-gọrin eyiti obinrin mẹrinla pẹlu nigbati nwọn fi mọto awọn Ọlọpa ko Oloye Awolọwọ ati awọn ẹgbẹ wa siwaju adajọ na.

Oloye Awolọwọ fi ye adajọ ile ẹjọ na ni ọjọ na pe otitọ ni ko si ẹni ti yio gbẹnusọ fun on ṣugbọn o tun fi ye ile ẹjọ pe eni ti ok n fẹ ki o gbẹnusọ fun on ni amofin kan lati ilu Oyinbo eyi ti orukọ rẹ njẹ Ọgbẹni E. F. N. Grathian. Adajọ ile ẹjọ na si ṣe ileri fun pe on yio gbe ọrọ na yẹwo.



Lateef Jakande

## ẸJỌ LORI GRATHIAN

Ni ọjọ kẹdogun oṣu kọkenla ọdun 1962 Oloye Awolọwọ pe Alakoso eto ofin ti apapọ Ijọba, Dokita T. O. Elias, ati Alakoso eto ile Naijira Alhaji Usman Serki ati fun ẹtọ lati le jẹ ki

Agbẹjọro fun on wa si ile Naijiria niwaju adajọ Ọgbẹni Udo Udoma ṣugbọn ile ẹjọ na da ẹjọ ti Oloye Awolọwọ pe nu eyiti Oloye Awolọwọ si ngbẹnusọ fun ara rẹ niwaju adajọ ṣugbọn adajọ ko gba ẹjọ ti ti Oloye Awolọwọ pe nṣe ni adajọ tu ẹjọ na ka

Ni ọjọ kọkanla oṣu kefila ọdun 1962 ni Dokita Sanyan Ọnabamiro ti ojẹ Alakoso eto Eko ni Ipinlẹ Iwọ Orun fi ye ile ẹjọ pe on jẹ ninu awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ati pe on pẹlu igbimọ Amoye eyi ti ẹgbẹ na da silẹ, Dokita Ọnabamiro tun sọ pe ise ti on ninu awọn Igbimọ Amoye na ni pe ki o kọ orukọ awọn ọga Ọlọpa ilẹ Naijiria lati le faramọ wọn. Dokita Ọnabamiro tun sọ pe awọn eni

WO OJU EWE KẸTA

# Ọgọta Apẹja Ri Sinu Omi

KALABA:—

Jinrijinni dabo gbogbo enia to wa ni ilu Calabar ati agbegbe rẹ n gbati irohin ati eriwo ẹkun de eti gbo wọn pe ọkọ oju omi kan si dinu sinu omi eyi to jẹ pe ọgọta ọmọ enia lo si ri sinu omi patapata.

Ninu irohin ti o de etigbọ wa lati ọwọ oniwe irohin wa ni ilu Calabar fi ye wa pe ninu awọn enia ti igbesi aiye wọn parun sinu ọmi fi ye ni pe awọn ọlọpa ti ri enia medọgbọn ko jade ninu wọn.

Irohin na tun fi ye wa pe gbogbo awọn enia medọgb ti awọn ọlọpa ko jade lati inu omi na pe gbogbo wọn ni ko si emi lẹnu wọn patapata. Ninu irohin lati ọdọ oniwe irohin lati Calabar sọ pe gbogbo awọn ẹbi ati oju lumọ awọn enia na lo si wa sibi ti jamba yi ti sẹlẹ ati pe awọn ero na ko lonka rara ti gbogbo awọn enia na lọkunrin ati lobinrin si sẹku ti ẹnikẹni ko ri ẹni gbara silẹ rara.

Oniwe irohin wa fi ye pe awọn ọlọpa si ti gbe oku awọn enia medọgbọn ti nwọn ri gbe jade lati inu omi na lọ si ile iwosan lakulaku fun iyẹwo

Oniwe irohin wa tun fi ye ni pe ki ṣe gbogbo awọn enia medọgbọn ti awọn ọlọpa ri gbe jade lati inu omi na ni nwọn ma orukọ wọn gẹgẹbi a ti nkọ iwe yi

Irohin lati ọdọ awọn ọlọpa ti ilu Calabar tun fi ye ni pe awọn ko mọ ohun to fa jamiba ọkọ oju omi na ati pe awọn ko ti le sọ kankan bayi titi nwọn yio fi ri gbogbo oku awọn enia yioku gbe jade ati inu odo na.

---

# YE IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan. 22–Feb. 20) Ọrọ apara yi ohan si ọ loni ṣugbọn gbidanwo lati ko ara rẹ ijanu bi bẹ kọ ijangbọn le bẹ silẹ, nitori na Iṣọra ni ẹbọ

PISCES (Feb. 21–March 20) Iwọ yio ri iweipe kan gba lati ọdọ ọrẹ kan wa, ṣe pẹlẹpẹlẹ nipa lifọwọ le iṣẹ titun.

ARIES (March 21–April 20) O tọ ki o pa iwa rẹ da ere nla ti iwọ yio si ma ri owo kọja ni irawọ rẹ jẹ lọṣẹ yi ṣo owo ọwọ rẹ ni nina.

TAURUS (April 21–May 20) Nigbagbogbo ni ọrọ ẹbẹ ma nje anfiyan fun ọ nipa aitete ni iyawo rẹ ti nwọn ko jẹki o fẹ ọmọbinrin ti o wu ọ.

GEMINI (May. 21–June 21) Bi o ba jẹ ẹniti o nla tẹtẹ, asiko rẹ niyi lati ṣe orire, owo tabua ni iwọ yio jẹ ati pẹlu Ọjọalaruba, ọjọ saturday lo le ko orire wa ba ọ

(CANCER (June 22–July 23) Bi o ba jẹ pe iwe ni iwọ nti iwọ yio ri ere pupọ lọjọ Monday ati ọjọ jimọ o dara fun ọ ki o kun kẹkẹ ologere lọsi ọna oko kan ṣugbọn maṣe yọju si ọrọ ọlọrọ Bi o ba nsiṣẹ akọwe

EO (July 24 – Aug 22 Iwọ yio ri oju ere ọga rẹ tobẹ ti yio ma fẹran rẹ dọba, Iwọ ma mura lati rin irin ajo kan laipẹ ojiji ni yio de

VIRGO (Aug 23 – Sept 23) O dara ti awọn enia ba gbe ọ niyi ki nwọn si ran ọ lọwọ ki o ba le ma foriti fun ilọsiw ju iwọ o ti ẹnikan ti yio ran ọ lọwọ ki iṣẹ rẹ le yọri si rere.

LIBRA (Sept 24 – Oct 23) O dara ki o ṣe sara, ki o si ma ṣe anu awọn alaini, iwọ yio ri oju rere agba ati ọmọde. gbajumọ iṣẹ rẹ

SCORPIO (Oct 24– Nov 22) Maṣe lọra lati bere imọran nipa iṣẹ rẹ eyiti ko ba ye ọ, iwọ osi ma ba iṣẹ rẹ niṣo pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ laisi ewu.

SAGITTAMIUS (Nov 23 –Dec 22) Akoko to lati fi ohun ti o nda aniyan le lori ṣiṣẹ ma ko iṣẹ ti ẹlomiran laipẹ iwọ o rin irin ajo ma yọnu si awọn ọmọde.

CAPRICOR (Dec 23- Jan 21) O dabi ẹnipe o fẹ ṣe aisan lo fi ara lelẹ lẹhin na iwọ o gbadun.

---


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Firms Patronise* MODUPE PRESS *Becuase Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 – Leave the rest to Modupe

We Granantee Neat Work And Quick Service

**Modupe Printing Press**

**16, Bamgbose Street**

Phone 21985, Lagos.


---


# I. C. M. Tọniki (100 Tablets)



Gbiyanju lati ma lo I. C. M. TỌNIKI nigbagbogbo I, C. M, TỌNIKI o wa fun Ọkunrin, Obinrin ati Alabo yun pẹlu. I. C. M. Tọniki o dara fun aini ẹjẹ to lara, o nfun ni lagbara, o si ntun ẹjẹ ṣe daradara. Bere fun eyọ igo kan, tabi dosini, odidi Apoti ( 50 dozes ) wa pẹlu. Ilera ni ogun ọrọ o Bere lọwọ Elegbogi yinbo ti o wa ni adugbo rẹ fun I. C. M. TỌNIKI (100 Tablets.)

Tabi ki o wa si ọdọ:—
MOSỌBALAJE MEDICINE STORES,
37, Palmchurch Street


---


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA **"DYNAMIREN"** TỌNIKI

ALE–BI–ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹṣẹ ti o kọ le jeun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo leyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu igbaba-dun ati alafia diro de ọ. Iyẹo daju Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

# Eyi ni awọn ọjọ Oja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE JULY 20 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Iṣabọ Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyededeji Ogburo, Ẹgbẹ Bọlokuta. Ijaiye-Orile |
| IJẸBU | Ilishan, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ẹpẹ Iọbalmuroko, Eriom |
| ẸGBADO | Ayetoro Ado-Odo |
| EKITI | Egosi Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ IṢẸGUN JULY 21 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ, Omidia Ilawọ |
| IBADAN | Itoko, Sojukonko, Tọwọbo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun —Ọwa, Ẹruwọn, Omu. Mamu |
| IJẸSHA | Osnu, Itagun, Odogbo, Idoko Itoko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ'RU JULY 22 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege, Ebute—Ikorodu |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọ Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibọfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| JẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ JULY 23 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun—Eko, Ojuwoye, |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbabo, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| BADAN | Pẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta, Ijaiyẹ—Orilẹ |
| IJẸBU | Ilisban, Odogbolu, Atan, Imọpe ṣara, Imọdi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaṣẹ, Iparindo |
| ẸGBADO | A'yetoro, Ado—Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyeduu |

## ỌJỌ ẸTI JULY 24 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun—Eko, Ojuwoye, |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Baba lokuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe ṣara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba. Imuroko, Erinmọọ Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ ABAMẸTA JULY 25 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin Badagry |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ Omida Ilawọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwn Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AIKU JULY 26 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBERẸ | Ikẹia, Agege Ebute-Ero Ọjọ Aj |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kaj Ajẹgunlẹ, Idọgọ, Olodo, |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imode |
| IJẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilọ-Idiẹmi |
| EKITI | Ikemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ AJE JULY 27 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Ibẹrẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Aketo o, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjau, Motẹlẹlẹ, |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaoṣu Ogera, Irolu, Itelu Ode-Rẹmọ Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunw Iboro |
| EKITI | Ilog o, Ishan. |

## IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ EJON'GBORO

**EKO**:— Jinijin' dabo gbogbo enia ti ngbe ni adugbo Broad Street ati adugbo Martins Street L'Eko nigbati mọto meji number Wk 916 ati number KT 5-08 kọlu ara wọn eyiti Ọkunrin kan si fara pa ninu jamba mọto na. Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe Ọkunrin na lọ si ile iwosan.

EBUTE MẸTTA

Ni dede agogo meji ku iṣẹju mẹdogun ni awọn Ọlọpa Ebute Mẹtta mu Ọkunrin Ọdaran Ole kan eyiti awọn Ọlọpa ka awọn ohun elo kan m ọ lọwọ.

Ọkunrin na si gba lẹsẹkẹsẹ pe nṣe lo on ji awọn aṣọ na gbe ni ile kan bayi lẹba ibudo Ọlọpa ni Ebute Mẹtta, Awọn Ọlọpa si ti ti ọdaran na mọle bayi.

CAIRO: Awọn olori Ijọba to ti gba ominira ni ile Afrika si ti de lati London si ilu Cairo lati ba awọn asoju ilu wọn to ti wa nibi ipade na ki awọn olori na to de fun ipade na. Awọn ara ilu Cairo si ti bẹrẹ si ni gba alejo titun miran bayi.

MANILA: Awọn ọlọpa si ti mu ẹdaran obirin kan to lọ ji ọmọ gbe ninu ọrọ ọdaran na fun awọn ọlọpa o sọ fun wọn pe o ti to ọdun mẹfa ti on ti mu ọmọ biorin na kuro ni ile wọn ati pe ero ọkan nipe yio ba on pẹlu bale on ti nwon ti fi ara silẹ fun ọdun diẹ sẹhin ati pe on yio si gba gẹgẹbi ọmọ on.

GAMBIA: Emi ọmọ mimọ Alufa J C. Patson Bisọpu Iwọ Orun ti awọn enia dudu ti yan Alufa M N C Scott ni Bisọpu fun orile ede ilu Gambia

EKO: Awọn ọlọpa si mu ọdaran ole kan eyiti o lọ gbe iwe ẹri ti nwọn ti nwa mọto ti numba rẹ jẹ 94341 orukọ to wa ninu iwe ẹri iwa mọto na si njẹ Yisa Bọla ti Adifa Street Ilọrin awọn ọlọpa si mu lọ si itimọle bayi

IBADAN: Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Oloye S L. Akintọla Alako ekini ti ile ẹkọ giga julọ ti Unifisiti ti Ifẹ lorin ọsẹ to kọja ọpọlọpọ ẹyẹ ni nwọn fi da Oloye Akintọla lọla ni ọjọ na.

KENYA Ọgbẹni Martins Shikuku akọwe agba fun ẹgbẹ Alatako ninu ile igbi iọ Asofin Ijọba Kẹnya ti kesi Ijọba e ki nwon le Asoju Ijọba Gẹẹsi jade kuro ni ilu Kẹnya kiakia.

# IROHIN IMOLE

IMOLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

No. 748. MONDAY JULY 20, 1964 (2D


## Ọkunrin Kan Bẹ Iyawo Rẹ Lori !

POTA!- Gbogbo awọn ero ti o wa si Ile ẹjọ giga lo patọlọ ti ẹsẹ ko si gbeji fun ogunlọgọ awọn ero nigbati awọn ọlọpa de ọdaran Jacob Kak imọ, ẹni ọdun mejidilọgọji ti o nṣiṣẹ akẹpẹ nigbekun wa si Ile ẹjọ ọjọ Ẹti ti ise ọjọ kẹtadilogun oṣu yi fun ẹsun apania.

Ẹsun ti awọn ọlọpa fi ka ọkunrin na ni wipe, ninu oṣun karun ọdun yi' nigbati ọdaran na mura lati lọ si oko ni yawo rẹ, Iyaafin Jacob ba bere Pe, ki o wa fun on ni owo onjẹ ki o to lọ si oko

Sugbọn ọdaran ba ko da iyawo rẹ lohun, bi o si ti fẹ bọ si ode leti maa lọ si oko ni iyawo rẹ ba lumaa ile ti ọ si ṣare wo, ada lo mu jade ti o si bẹ iyawo ẹ lori.

Bi ọdaran na ti se bayi tan, ti atiwo si ta gẹẹ, ni gbogbo enia ba sare de, odaran na si pẹlugbẹ. ni ojo keji ni awọn olọpa lo si mun nibito o lugọ si

Nigbati adajo na ẹgbẹni H. Bethnel gbo ẹjo na tan, o fi gege lu ehin kẹkẹ, osi pasẹ pe ki nwo lo be ọdaran na lori ninu ogba ẹwọn Ẹyin ti ulu Iyawo nyin ẹro di owo nyin o.

# Ọba Alaiyeluwa Muṣẹndiku Adeniji Keji Filẹṣaṣọbora !

LATI OJU EWE KINI

na ni ọja ni ọjọ isinku Ọba" ṣugbọn awọn-Olọpa ti nwọn duro ni agbegbe Isalẹ Eko ko gba awọn enia na laiye lati ṣe bi nwọn ti ṣe fẹ ṣe.

Ni deede agogo mẹrin irọlẹ ni ẹsẹ gbogbo awọn oloye, Ọba Alade, Minista, ati awọn Bọrọkinni ilu Eko ti pe sansan ti aye ko si si fun ogunlọgọ awọn enia ti o pọ lẹhin ki nwọn to de.

Lẹhin na ni nwọn wa se isin igbẹhin ni ọna ti Musulumi fun ologbe Ọba Adele ṣugbọn Ejongboro fi ye wa pe, awọn enia na ti pọju ti o fi jẹ wipe on ko le sọ bi Lẹmọmu Agba fun ilu Eko Imam Alhaji Liadi Ibrah'm lo se isin ku na tabi on kọ.

Nigbati n•ọn pari isin ra tan, ni awọn oloye wa bẹrẹ eto ti wọn gẹgẹbi iṣẹ Idalẹ ilu Eko ni ọna pataki ti nwọn fi nse isin ku awọn Oba.

Ni deede agogo mẹrin abọ ni awọn oloye onifila funfun wa gbe oku Ọbe na lọ si "Ile Igbẹhin."

Oniruru ilu ati ijo ni awọn enia na njo, ṣugbọn ohun ti o ya gbogbo enia lẹnu julọ nibẹ ni Ijẹt ni wipe, bi awọn enia na ti njo igbe ibosi "Awo! Awo!! Awo!!!" ni gbogbo wọn nke tantan.!

Oni ohun wa kan ran wa leti pe; ni ọjọ Aiku ti ise ọjọ kejila osu yi ni Ọba Muṣẹhindiku Adeniji Adele keji wa'ja ninu Iga rẹ lẹhi aisan diẹ ti o ṣe e.

Onirohin wa na tun ta wa lolobo pe, ẹni adọrin ọdun (70 years) ni ologbe Ọba Adeniji Adele ki o to wa'ja. Ninu ọdun 1894 ni nwọn bi Ọba Adele keji ni ilu Eko. Ninu ọdun 1949 lo si jẹ oye Ọba.

Awa oniwe irohin Imọlẹ gbadura pe ki Hallah tẹ ologbe Ọba Alaiyeluwa Muṣẹhindiku Adeniji Adele keji si afẹfẹ rere ki o si se baba fun awọn ọmọ ti Ọba oninu re na fi silẹ

LATI OJU EWE KINI

awọn enia mejila ti awọn lero pe, nwọn o ṣe iranlọwọ lati sọ ohunti o da ija na silẹ

A lero pe awọn eni na y'o farahan niwaju adajọ ni owurọ ti bi nwọn ba si si wadi ọrin na si ẹo tun ima a gbọ o'


TRADITION REFLECTED IN PROGRESS

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.



Printed and Published by Mocupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 20/7/64.